LIBRARY
18 DEC 1965

# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ *ORE AIYE TENI* GBOGBO LAWA

No 1,583 SATURDAY DECEMBER 11, 1965 (2D)

## Okunrin Kan Yin'bọn Pa Ara Rẹ

KANO:— Jinnijinni dabo gbogbo awọn enia ti nwọn lọ si ọja ti a npe ni Sabon Gari Kano Ipinlẹ Ariwa ni kutukutu owurọ ọjọ ọjọ'Bọ ti iṣe ọjọ kẹsan oṣu yi nigbati okunrin lebira ti ile iṣẹ Ijọba ibilẹ ilu Kano bin u yin ibọn pa ara rẹ nigbati okunrin na jijọ ki ara wọn pẹlu awọn enia ti o jijọ ngbe inu ile.

Iṣẹlẹ nla yi ṣẹlẹ ni adugbo kan ti nwọn npe ni nomba 5 Gold Coast Road Sabon Gari, Kano ni dede agogo meje owurọ ọjọ na eyiti okunrin na fi yin ibọn kan ti nwọn pe ni "Double Barrel.

Oniwe irohin wa fi ye wa ninu irohin rẹ pe okunrin lebira ninu ile iṣẹ ti Ijọba ibilẹ ilu Kano ati pe okunrin na si bi ọmọ marun silẹ

Ninu ọrọ awọn enia ti nwọn jijọ ngbe ile ti ọkunrin na ngbe fi ye oniwe irohin wa pe ko ti pe ju iṣeju marun bayi ti on pẹlu okunrin na jijọ ki ara wọn eyiti on si gbọ iro ibọn eyiti o jẹ wipe okunrin na lo yin ibọn fun ara rẹ ninu yara rẹ.

Okunrin na ti o fi ọrọ na nye oniwe irohin wa tun ṣe alaye pe gẹgẹbi on ti gbọ iro ibọn ni on ba yara sare jade eyiti on si ba okunrin na ninu agbara ẹjẹ ti o dabi ẹnipe ọjọ lo nrọ.

WO OJU EWE KẸFA

# NWON DANA SUN ỌKUNRIN KAN LAAYE !

IJẸBU-RẸMỌ:— Ko ju wakati mẹwa ti awọn olori ẹgbẹ oṣelu awọn Ọba, Ijoye ati awọn Aṣoju Ile Igbimọ ti Ijọba Ibilẹ Ijẹbu Rẹmọ ṣe ipade kan lati fi opin si iwa ti awọn janduku ọmọ ẹgbẹ oṣelu kan nhu nipa pe ki nwọn ma pa enia tabi pe ki nwọn ma dana sun ile onile tabi ile awọn olori ẹgbẹ oṣelu ni awọn enia kan tun dana sun ile marun ni awọn ilu ẹkun Ijẹbu-Rẹmọ.

Ninu ipade ti awọn enia na ṣe pẹlu ọga agba awọn lori pe ki nwọn maṣe tun yin ibọn pa ara wọn eyiti ko ju wakati mẹwa ti ipade na lọ si opin ni awọn enia na tun bẹrẹsi dana su, ọkunrin kan laaye eyiti o jẹ pe ninu ina na ni ọkunrin na ku si

Ninu irohin pe nwọn dana sun ile ni ọjọ ọjọ' Bọ ti iṣe ọjọ kẹsan oṣu yi ni a ti gbọ lati orile-oke abuleko kan lẹba Shagamu eyiti o jẹ wipe gbogbo ile na lo jo ti gbogbo ogiri na si wo lulẹ patapata eyiti o fi jẹ wipe okunrin kan ku sinu ina na.

Ninu irohin miran lori ile ti nwọn ndana sun ni lati Ode – Rẹmọ eniti awọn enia na tun lọ dana sun ile pẹẹtsi nla kan bayi eyiti o fi jẹ wipe gbo ile na lo jona patapata ni ọsan gangan ọjọ ọjọ ọjọ 'Bọ ti iṣe ọjọ kẹsan oṣu yi.

Bakanna ni irohin tun de ọwọ wa lati ilu Shagamu ti iṣe Olu ilu fun ẹkun Ijẹbu-Rẹmọ pe awọn enia kan tun dana sun ile mẹta kan ni Owurọ ọjọ ọjọ 'Bọ ti iṣe ọjọ kẹsan oṣu yi.

Oniwe irohin wa tun fi ye wa pe awọn Ọlọpa ti bẹrẹsi ni wa gbogbo agbegbe ibiti awọn iṣẹlẹ ina na ti nṣẹlẹ ati pe awọn Ọlọpa ko ti ri ẹnikankan mu ninu awọn enia to ndana sun awọn ile na ni ẹkun Ijẹbu – Rẹmọ.

Irohin tun fi ye wa pe awọn enia ilu Ilishan nioiti adọta ile ti jona lati ọwọ wọn ọmọ ẹgbẹ Oṣelu kan pe awọn enia na ti nwọn sa asala fun ẹmi wọn ti npada bọ si ilu na bayi lori ohunti o ti nṣẹlẹ ninu ilu tẹlẹ lati ọsẹ to kọja lọ yi.

## Owo-Oṣu Awọn Ọba

Bakanna ni irohin tun fi ye wa pe ninu awọn Ọba ati Ijoye mẹrinla ti Ijọba ibilẹ ti Ijẹbu-Rẹmọ da owo oṣu wọn duro ni a gbọ pe Ijọba ibilẹ ti ẹkun Ijẹbu Rẹmọ ti fẹ san owo oṣu awọn Ọba ati Ijoye mọkanla pada fun wọn bayi.

Ninu ipade kan ti awọn Aṣoju ti ijọba ibilẹ ti Ijẹbu Rẹmọ ṣe ni ọjọ ọjọ'Ru ti iṣe ọjọ kẹjọ oṣu yi ninu Aafin Ọba Moses Awolesi Akarigbo ti Ijẹbu-Rẹmọ ni nwọn ti ṣe ipinnu lati ma san owo oṣu awọn Ọba na fun irohin tun fi ye wa pe Ọba Moses Awolesi Akarigbo ti Ijẹbu Rẹmọ si wa nibi ipade na.

Ni ipade ti awọn enia na ṣe ni awọn Ọba ati awọn Aṣoju Ijọba ibilẹ ti Ijẹbu Rẹmọ jijọ fi ọwọ si adehun iwe na nibi ipade na.

Ninu awọn Ọba ati Ijoye ti nwọn da owo oṣu wọn duro ni ẹkun Ijẹbu-Rẹmọ ni Ọba Moses Awolesi Akarigbo ti Ijẹbu-Rẹmọ Odemo ti ilu Ishara, Alakẹnnẹ ti ilu Ikẹnnẹ, Ologere ti Ogere, Ẹlẹpẹ ti ilu Ẹpẹ Lẹmọ ti Ogijo, Lewo ti Odelewo, Alakaka ti Akaka Onipara ti ilu Ipara, Oniolu ti Irolu, Ọbọ Orile oko ra awọn;miran.

## Adehun

Ninu adehun ti awọn Ọba ati awọn Aṣoju Ijọba ibilẹ na jijọ ṣe nipe:

Ko gbọdọ si pe ẹgbẹ oṣelu kan fi iya njẹ ẹgbẹ oṣelu ti ko ṣe ọmọ ẹgbẹ ti wọn tabi Alatako ẹgbẹ wọn.

Ko gbọdọ si pe awọn Ijọba ibilẹ kan ni ẹkun Ijẹbu Rẹmọ tun nhalẹ mọ awọn Ọba tabi awọn Ijoye wọn ati pe ko gbọdọ si pe enia kan tun nyin ibọn tabi ki nwọn da rogbodyan silẹ ni ẹkun Ijẹbu-Rẹmọ eyiti o nṣẹlẹ larin awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu.

Aworan yi ni ti Ọgbẹni Ganiyu Dawodu, Alaga Ijọba Ibile Ilu Eko nigbati o fi nrẹrin si Oniwe Irohin wa ati gbogbo awọn enia ti nwọn wa niwaju ile iṣẹ rẹ l'Eko [illegible]

Alaga titun na ṣe alaye fun Oniwe Irohin wa wipe, on yio sa gbogbo agbara ti o wa ni ikawọ on lati rii wipe ilu Eko dara ju bi o ti wa nisisiyi lọ, paapajulọ, on yio ṣe iṣẹ on na ni o ju mejeji ti awọn enia yio fi mọ wipe, Ọdọmọde ti o mọ nipa eto ati ilọsiwaju, ni awọn gbe iṣẹ le lọwọ.

O tun ṣe alaye wipe gbogbo awọn Oju Ọna ti ko dara l'Eko ni Ijọba yio tun ṣe pese awọn ohun mere mere iṣere fun awọn Ọmọ ile – iwe yika gbogbo ilu Eko.

Ni ipari, Ọlọla Ganiyu Dawodu sọ wipe ijọba Eko yio tun pese bọọsi mọkanleladoje (131) fun awọn ara Eko [illegible] fun gbogbo awọn oṣiṣẹ lati ma a lọ si ibi iṣẹ, ti ko fi ni si idaduro fun wọn.



Ogbẹni G. O. Dawodu
Alaga Ijọba Ibilẹ Eko

LAGOS CITY COUNCIL

ROWE PARK SWIMMING POOL
CLOSURE FOR REPAIRS

It is hereby notified for general information that due to replacement of a number of tiles at the bottom of the Swimming Pool, the Rowe Park Swimming Pool at Yaba will be closed to the public as from Friday the 10th December 1965 till further notice.

S. J. MAYAKI
TOWN CLERK

City Hall
Catholic Mission Street
Lagos.
10th December, 1965.

# BI AWỌN DOMISILE SE NTỌJU AWỌN ABOYUN

EKO:- Ni deede agogo mẹta ọsan ana ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu y ni a r iwe ipe kan gba lati olu ile iṣe awọn ọjọgbọn Onişegun Domisile ilu Eko wipe nwọn fẹ şe eto odun idaraya ọdun Keresimesi fun gbogbo awọn om de ni igboro ilu Eko ni oni ọjọ Abamẹta ti iṣe ojọ kọk nla oṣu yi ninu ile iwe awon Ijọ Ọloran ti nwọn pe ni "Christ Cathedral Schtol" ni Opopo Broad Street, Eko.

Ọkan ninu awọn ọga Agb inu ile ẹ na se alaye fun Oniwe Irohin wa wipe aw n ti fi iwe pe ra şe si gbogbo awọn eni saraki sarak awọn bọrọkin enia at awọn enia jank n jank n yika gbogbo igbo ilu Eko lati wa s ibi a e idaraya ti awọn yio se fun awọn ọmọde ninu Ile iwe na ni irọlẹ oni

Iyafin Adeso e tun şe alaye siwaju niu ọrọ rẹ wipe bayi ni aw n ma nse fun awọn omọde ni ọdun-dun lati fi k awọn ọmọ ti nwọn b bi sinu ile ti awon si şe it ju won lehin ti nw n ti bi won omo na tan.

N g ati ojo odun Keresi-m si a ti u s d dẹ aw n yio t fi iwe ipe rẹ şẹ si awon omode na ati awon obi won lati wa si ibi are idaraya na ti gbogbo wọn yio se peşẹ sibẹ sanmusa-mu ni ojo ti nwo y o ba se are na fun gbogbo awo omode na.

N gb ti a on omode na ati awon obi won ba de awon ag e i ati awon oga won gbogb ni nwo ylo ki awon omode na ku orire ti nwon yio si tun ba awon aboyun gogbo yo oltoripe aiti odun ba de ba laiye ti o s de ba ni aaye, ki oluwarẹ dupẹ ki o si tun fi ogo fun Ọ ọrun Olodu mare fu dida ti o da ẹmi rẹ si laiye lati tun le ri odun titun na lẹkan si i

Iyaafin Adeoye tun şe alaye pelu ninu oro rẹ pe awon alasẹ ile işẹ awon ti, toju awon ohunti nwọn yio fi se ọdun na sile fun awọn alaboyun pẹlu awọn oko wọn pẹlu gbogb a o enia jankanjankan ni ile pẹ lu awọn osisẹ ile isẹ Imọto to ni orisirisi

Nigbati oniwe w n de inu ile iwe y ni ana, nwon ti ta orisirisi awon sia ati ina alatara si gbogbo inu ile ati ode ninu ọg a ile iwe n f in palẹmo ohunt aw n enia n yio şe ni irọlẹ oni

Nigbati oniwe Irohin wa bere lọwọ ọkan ninu awon



Aworan oke iwe yi ti e nwo ni ti awon osisẹ ile işẹ Imọtoto Domisile nigbati nwon lọ wo obinrin kan lẹhin ti obinrin na ti bimọ tan ninu ile rẹ ti nwọn si nfi han an bi yio ti se maa tọju omo re lẹhin ibimọ, nigbati nwon si toju ọmọ na tan, nwon pada si ile won. Igba meji ni nwọn nlo ile Alabiyamọ na ni ojumọ nwọn nlo si ile rẹ ni agogo mẹfa ni kutukutu owurọ ati agogo mẹfa irọlẹ.

oşisẹ inu ile isẹ na ni ana wipe ki ni awọn ohun ti nwọn yio fi se awọn enia na ni alejo ni irolẹ yi nigba ti nwon ba de

Oşişe na se alaye wipe awọn alaşẹ ile işẹ na ti to-ju awọn ohun elo ni orisi-risi sile. onj, orisirisi eyiti ẹnu maa nje, ilu jaju, Sake re, ti A al ni nwọn ni pe s sile fun awọn enia na lati n se won ni alejo ni-gbati nwọn ba de şibi are idaraya na ni irọlẹ oni.

Ni afikun, osise na sọ wipe, awọn alasẹ ile işẹ

Imotot na na ti t n p awọn onilu ati awọn onijo lati wa da awọn enia ti nw n yio wa si ibe loni laraya,

Awọn osisẹ Domisile yi nwọn maa ntoju Aboyun nigbati nwọn ba fẹ bi ọmọ, awọn Alasẹ ile ise na ti se eto ti o fi je wipe, ninu ile ni awọn Aboyun yio bimọ si nipa iranlọwọ wọn ala mojuto ti nwọn nse

Nigbat awọn Aboyun na ba bi ọmọ tan, nwọn yio ma lọ wo won ninu ile wọn lẹhin wakati mẹrin mẹrin ti nwọn yio ma se itoju iya ati ọmọ tuntun na, bayi ni nwọn yio si maa se fun odidi ogoji ọjọ

Ki awọn Aboyun ti bimọ ni nwọn yio ti maa lọ si ile işe wọn lati ma lọ gbe ogun ti nwọn maa lo nigbati nwọn wa ninu oyun

Bi n o ba ti se nlo si ile işẹ won ni awon alase ile isẹ na yio maa sọ awọn ohun ti o ta dara fun won l ti ma je, ati ti ọ ye won lati ma wo, bi ọ ti se yẹ ki nwon maa se itoju ile wọn, iru onjẹ ti o yẹ ki nwọn maa jẹ ti i ti nwon yio fi bimo, nigbati o ba se di ojo ikunle, awon na n won yio wa se itoju won ninu ile won a ti row irosẹ ni awọn Aboyun si fi nbi-mọ won

Bayi ni a o duro ni oni şugbọn ni osẹ ti nbọ eo tun maa gbọ awọn ikan miran ti awọn Domi-sile tun nse fun awọn Aboyun ni-gbati nwọn wa ninu oyun ati ni-gbati nwọn ba bimọ wọn tan pẹlu orisirisi awọn anfani ti o wa fun awọn Obinrin lati maa lo si odọ wọn fun ojulowo imọran ati iranlọwọ

Şugbọn, Oniwe Irohin wa Ejon gboro yio lọ si ibiti nwọn yio gbe se idaraya na ni irọlẹ oni gbogbo ohunti nwọn ba si se nibẹ pẹlu aworan awọn enia ti nwọn ba lọ sibẹ ni ni eo ri ka ninu iwe Irohin wa ni ọsẹ ti nbọ yi

WO OJU EWE KARUN FUN AWORAN MIRAN



## Iwe si Olotu Irohin Imole

### Ẹ Mojuto Alafia Ilu Eko

Mo bẹ enyin alamojuto ilu Eko ki ẹ ran wa lọwọ lati ba wa mojuto awọn jagudi, ole ati aje leju onile ti o wa ni ori gadi kereni, iwa ti nwọn nhu nibẹ l-ti agogo kan alẹ si mẹrin owurọ ko dara to rara, nwọn ki ifi oju enia balẹ rara ni asiko ti ọna bada.

Bi enia ba gun basikulu kọja ni asiko ti mo darukọ yi, awọn Ọlọṣa yi yio wa ọna lati mu oluwarẹ ki nwọn gba awọn owo ti o ba wa lọwọ rẹ paapa basikulu ti o ba gun.

Awọn ọlọpa si ri awọn enia wọnyi, nwọn ko jẹ lọ kọ wọn, a fi ki nwọn lọ maa mu awọn ob nrin ọlọ ja ati awọn ti nkiri oja pẹlu awọn ti o ba patẹ oja wọn si ojude wọn.

Mo bẹ alaṣẹ awọn ọlọpa ki o ran wa lọwọ lati gbogun ti awọn igara ti o wa ni ori kereni ki nwọn ye ma pa enia ni ẹkun mọ.

Olotu ẹ ku iṣẹ o

Emi ni
S O Ọladimeji
EKO.

### A Nfẹ Oda Ni Oju Ona Oko Odẹ

Olotu jọwọ gba mi n aye rẹ pẹlu nu iwe yin ti o kun fun ọgbọn ati o e lati ba awọn ol ṣẹ Ijoba Oke Ọdẹ pa pa Ijoba Ipinle Ari a soro l ri ipo ti ilu Oko Ọdẹ wa lati awọn ilu ti o wa ni Ipinẹ Ariwa

O ti to ọdun meta ti a ti nkesi Ijoba Ipinle Ariwa lo ri ipo ti ilu wa wa ni asiko nti ripe ilu wa ofe atunṣe lo polopo paapa a fe oda ni awon ilu to wa ni ile Naijiria

Ọna wa na je ti o ṣe pata ki fun awon onimoto to ba nlo si ona Ilobaja tabi awọn ti o ba nlo Oke Iya, ibe je ona ti opolopo awon onimo to ma a gba o tun je ona ti abuja ewiti o ndin owo epo awon onimoto ku

Awọn ọna yi ti bajẹ pupọ agbara ti gbẹ koto si awọn oju ona na bi mọto ba koja nibẹ ni ekan soso a fi ki Onimoto gbe mọto na lọ fu awọn atu mọto ṣe,

Be ni a w a nsanwo ori si apo ijoba Ipinle Ariwa bi awon ilu yoku

Mo dupe lowo re Olotu

Emi ni
Salawu O Adeyanju
OKO—ỌDẸ

### Roșiji So Oro Ti O Dara

Olotu dakun gba mi ni aye ranpẹ ninu iwe rẹ olo yin mi mọ lati fi esi si ọrọ kan ti o jade lẹnu Oloye Ayọ Roșiji, minista eto Irohin fun Apapọ Ijoba ni ọjọ keji ti a gbọ abayọri eto ibo ti nwọn di ni ilu Eko eyiti o fi ẹnu kan pe, awon enia Eko fi ọkan tan ẹgbẹ Afẹnifere ni nwọn ṣe dibo fun ẹgbẹ na ti nwọn si kọ ẹgbẹ Alakukọ pẹlu ẹtan wọn,

O wa pari ọrọ rẹ na pe lalpẹ fia ti o wa larin ẹgbẹ Demọ pẹlu Ọlọpẹ koni pẹ pari bayi ti awọn yih tan jijọ ma ba ọrọ awọn lọ,

Nitootọ ni ọrọ ti Roșiji sọ, ṣugbọn ewu re ko pe on ko ṣe emọ Aputan ṣugbọn ag tin lo ni iwa on to bi dudu enyin ẹgbẹ Demọ ni e ṣe ara nyin, ijẹkujẹ ati apanin lo yọ nyin ninu ẹgbẹ Ọlọpe, ẹgbe Demọ ti e siṣe ko gbojumo ni arin ilu,

Mo bẹ enyin omo ẹgbẹ Demo pe ki e tete wa dapo mo egbe Afenifere ki ka na le ma lo dede nitorina enyin omo Demo e tete pada si ese arọ

Ẹ ku iṣe olotu ajinde ara yio ma je,

Emi ni
L Aladesanmi
ONDO


### WANTED

Advance Apprentice and Apprentice Printers,

Apply In Person

Irohin Imọlẹ's Office

16, Bamgbose Street,

LAGOS.



## Ha Kini eleyi O




OGUN A PA YANMU—YANMU LORI ERIN MẸTA NI

Three Elephant Brand mosquito coils dara pupọ A n O dara ju gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ

O npa yanmuyanmu ninu ile ni kiakia orun rẹ si da ra pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ Bakanna ni o si tu yara pa ayan ati idun

Tete lo ra packet ogun yanmuyanmu Three Elephant Brand coils tirẹ loni, ki o si dan wo, iwọ yio ri bi o ti ṣe pa gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti iwọ ati awọn ọmọ rẹ yio si sun di radara

Ki o ri daju pe ogun yanmuyanmu o cri erin mẹta yi ni nwọn mu un ọ

Three Elephant mosquito Brand coils yi wa ni ṣọbu ti ile itaja kakiri orile ede yi

DISTRIBUTORS
AMOS GBENLE & BROTHERS
34, Decemo Street, Lagos
6 & 11 Balogun Street, West
LAGOS



BERE FUN OJULOWO ADI ELEGBO

## "Congreve's Iodo Form--Ointment'



Atamatase ni egbogi "ADI-ELEGBO" yi i fun itoju ebo ebo orisirisi "EGBO—ẸSẸ" n k akia bi o ti wun ki jọ rẹ t le pẹ to, Adielegbo yi ko ni ẹgbẹ nipa wipe awa ko idọti ii bi ẹr gbogbo ti o ba wa loja egbo patapata jade oju re yio si mo daradara .Lẹhinna oju egbo ti o ba jin si u yio jeki oju re ru wa soke, yio si pọn daradara run bakaru ko si mo se cwere ni yio si san patapata. Alafia de si ọ niyen :

Ri daju gbangba wipe awon sobu ti a da oruko won si isale iwe yi ni ẹgbe ranse lọ ra Bibeko awon Eleru tabi onjibiti yio ta 'Adamodi' re fun o maṣe gba ra o.

Bere egbogi yi ni ṣobu awon :—

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palm Church Street Phone 22787
ATI NI ṢỌBU
IṢE OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA
IBADAN

## Ofin Koni Le Gbeie Tun Bere

IBADAN:— Ni deede agogo mẹwa alẹ ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ keje oṣu yi ni irohin kan tun de ile iṣẹ wa pe Ijọba Ipinlẹ Iwọ Oru Naijiria ti tun ṣe ofin ki on le gbele si agbegbe Agẹge, Ikẹja, Mushin, Shomolu ati agbegbe ijọba ibile ti Ajerọmi eyiti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun tun fi ṣe ofin pe ko gbọdọ si ẹnikẹni ti o gbọdọ jade lati agogo meje irọlẹ titi di agogo meje owurọ ọjọ keji

Bakanna ni irohin tun fi ye wa pe Ijọba ibilẹ ilu Ibadan tun ti ṣe ofin kan pe ko gbọdọ si ẹniti o gbọdọ jade lati agogo meje owurọ ni ilu Ibadan eyiti o bẹrẹ lati ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ keje oṣu yi ati ọjọ kẹrinla oṣu yi ni yio pari.

Irohin na tun fi ye wa pe awọn Ọlọpa lo ṣe eto yi lati fun Ijọba ibilẹ ilu Ibadan laṣẹ lati ṣe ofin na.

Bakanna ni irohin tun fi ye wa pe ki yio si ipade ode gbangba lati ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ keje oṣu yi titi di ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kọkanlelogun oṣu yi eyiti o jẹ pe jakejado Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ni ko gbọdọ ti si ipade ode gbangba

Ṣugbọn ofin ki oni e gbe le ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ṣe si agbegbe Mushin, Agege, Ikẹja, Ajerọmi ati Shomolu yio lo ọsẹ kan ki o to le ka ẹsẹ nilẹ.

Bakanna ni irohin tun fi ye wa pe Oloye S. L. Akintọla ba awọn Minister ti o yan ati awọn Olori ẹgbẹ Dẹmọ ṣe ipade bọnkẹlẹ kan ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kejo oṣu yi ninu ile Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Oniwe irohin wa ni ilu Ibadan fi ye wa pe ko si ọrọ kankan ti awọn Olori ẹgbẹ Dẹmọ to ṣe ipade na sọ fun awọn Oniwe irohin lati le jẹki nwọn mọ ohunti wọn jinroro le lori nibi ipade bọnkẹlẹ ti awọn ẹgbẹ Dẹmọ ṣe.

Ṣugbọn ohunti awọn enia na jinroro le lori ni eto nipa ipade ti awọn ọmọ ẹgbẹ na ṣe ninu Ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ na

Oniwe irohin wa tun fi ye wa pe bakanna ni ọga agba awọn ọlọpa ni Ipinlẹ Iwọ Orun ọgbẹni Odofin Bello tun ba Gomina Ipinlẹ na Oloye Joseph Ọdẹlẹyẹ Fadahunsi ṣe ipade kan ṣugbọn nwọn ko sọ ohunti nwọn jiroro le lori

Ni alẹ ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ keje oṣu yi ni Alhaji D. S. Adegbenro lọ ba Gomina Ipinlẹ na ninu Ile rẹ ti o si ṣe ipade kan ṣugbọn ko gbọ ohunti awọn mejeji jijo sọrọ le lori.

Lẹhin eyi ni Alhaji D. S. Adegbenro tun ba awọn olori ẹgbẹ itẹsiwaju (UPGA) ṣe ipade kan Irohin fi ye wa pe ohunti awọn olori ẹgbẹ yio sọrọ le lori nipe awọn ko fi ara mọ abayọri ibo ti awọn di si Ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria


## Iwo Ha Nfẹ Ile LEko Bi?

| | | |
|---|---|---|
| Room | | £3 |
| Room | | £4 |
| Room | | £5 |
| Room / | Parlour | £6 |
| Room / | Shop | £15 |
| Flat | (Lgos) | £20 |
| Flat | (EB) | £25 |

Ti o ba nfẹ okan ninu awọn ile wọnyi yara tete lo ri Ọgbẹni ODUS:— 187 Bamgboṣe Street Lagos ni deede agogo merin irọlẹ si agogo mẹfa irọlẹ. ijafara lewu anfani nla kan ni eyi jẹ fun ọ pe o ri ile l'Eko


## YE IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 22 Feb 20) ayọ ni fun ọ ni gbogbo ọjọ oni pẹlu ara lile ti ko si ohun kan lati damu rẹ

PISCES (Feb 21 Mar 20) Tun gbogbo nkan ti o ti nse bẹrẹ ni arin ọna ti awọn enia yio fi ma sọrọ rẹ yio dara fun ọ

ARIES (Mar 21 April 20) Mase fi ọwọ le ohun titun kan ti iwọ ko seri ero ti nwọn ngoa si ọ nipe ki a le fun Ọlọrun

TAURUS (April 21 May 20) Alejo kekere kan yio ba ọ jẹ ṣugbọn alafia yio de ki o to to asalẹ

GEMINI (May 21 July 21) Mase lọ fi owo fa ijongbọn wa ba ara rẹ jẹ ki o di igbati ile ba ki o ma ba ṣina

CANCER (June 22 July 22) O ni lati wa akoko pataki lati fi wa isẹ se loni iwọ yio si ri iṣẹ se

LEO (July 23 Aug 22) Tẹlẹ gbogbo nkan dun lo ni ko njọ loju ṣugbọn mase se iru rẹ lo mọ

VIRCO (Aug 23 Sept 23) iwọ yio ri oju rere ọrẹ rẹ gba tohẹ ti iwọ ko gbọ gbe ore na ti o se fun lailai

LIBRA (Sept 24 Oct 23) Obinrin gbajumọ kan yio ba sọrọ fifẹ ara ẹ ni bi oba mura ọrọ na yio di iyawo rẹ.

SCORPIO (Oct 24 Nov 22) ina rere rẹ si awọn enia yio mu ọpọlọpọ ire ati owo wa fun ọ

SAGITTARIUS (Nov 23 Dec 21) Mase ba ẹnikan sọrọ asiri ki awọn ma ba se ofofo pe iri rẹ poju

CAPRICORN (Dec 22 Jan 21) Mase se ohun to to ni aseju ki a ma ba pe ọ ni eleke


# Kere o Kere o!
# Akiyesi Pataki




Awa na le jẹri wipe Ojulowo hanunhanun Egbogi n LEOPILLS awa na nlo ni Gold Coast (Ankara Ghana pẹlu meji rẹ ko si ninu gbogbo orisirisi Egbogi ti o wa ni Ilẹ Naijiria

A wa na njẹwọ ni Igboro Ilu Eko, Irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia tọmọde t'agba ni asiko yi ti nwọn fi ṣe ọrọ ati orin larin ara wọn nipa Egbogi Jamani olokiki yi ti nwọn npe ni LEOPILLS

Imọran awọn Dokita Oyinbo ti nwọn nṣe iwadi Egbogi LEOPILLS. yi kan ṣọ wipe bi o ti lagbara to ati bo jẹ Ojulowo girikl ati atamatase fun "JẸDIJẸDI" bi o tiwu ki ọjọ rẹ pẹ to bẹ na ni nwọn si tun fi ọwọ sọya tabi po ileri fun gbogbo awọn ti amodi tabi iju, Igbẹ sise, aiko ri igbonsẹ deede, inurirun nigbakugba ara wiwo, Ẹsanri ẹhin didun sisan ati aiko riran kedere ko doro buruku ara, aisan Onigbameji ati orisirisi arun miran gbogbo pẹlu

"Wipe nwọn yio ri alafia ni kiakia ti nwọn nba egbogi LEOPILLS nitoripe o tun ma tun ẹjẹ ṣe enia nipa sise di ọtun.

RANTI PE ALAFIA LOGUN ORỌ IJAFARA SI LEWU PẸLU.

IYE OWO EGBOGI LEOPILLS:— Igo nla si'e mẹfa abọ (6/-6 pere Igo kekere ṣile mẹta abo 3/6) pere. Bere Ojulowo Egbogi miran fun orisirisi Arun ti e ba fẹ ni Ṣọbu awọn:—

ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street,Yaba

# Asobade Ori-re Are Boolu

## Eglish DiV. 1

| | | |
|---|---|---|
| Aston v | Everon | xI |
| Blackbury | North'pton | I |
| Blackpools | Stoke | 2x |
| Fulham | Burnley | x2 |
| Leeds | West Brom | I |
| Leicestea | Sheff W'ad | : |
| Liverpool | Ase al | I |
| Sheff, Utd | Nott'm For | I |
| Sunderland | Man Utd | x2 |
| Tottemham | Chelsea | x |
| West Ham | Newcastle | x |

## English DiV- II

| | | |
|---|---|---|
| Bristol C | Middisbo' | I |
| Bury | Portsmouth | I |
| Card ff | Pr s on | I |
| Carlisle | Crystai P | xI |
| Coventry | Huddersf'd | x2 |
| Derby | Charit n | x |
| Man City | Leyton Or | I |
| Norwich | Bolton | xI |
| Rotherham | B rm'gham | I |
| South'pton | Plymouth | I |
| W ,ves | Ipswich | I |

## English Div III

| | | |
|---|---|---|
| Br ghton | Shrewsbury | Ix |
| Exeter | Oxford | x |
| Gi lingham | Workington | x |
| Hulifax | Bristol R | I |
| Mansfield | Brentford | xI |
| Milwall | Wa't. ll | xI |
| Oldham | Bournem'th | xI |
| Peterboro' | Swanfea | I |
| Q. P Rangers | Grimsby | x |
| Re ding | York | I |
| Scunthoorp | Swiudow | I |
| Watford | Sourhend | I |

## English Div IV

| | | |
|---|---|---|
| Barnsley | Torquay | x |
| Bradford C | Newport | 2I |
| Chester | Southport | I |
| Colchester | Gbesteef'd | xI |
| Crewe | Aldersbot | I |
| Darlington | Barrow | x |
| Lincoln | Hartlep'ls | x |
| Nott's C | Doncaster | I |

| | | |
|---|---|---|
| Port Vale | Bradford | I |

## Scottish Div V

| | | |
|---|---|---|
| Dunf'mline | Stirling A | I |
| Celtic | Hibernian | 2 |
| Dundee | Hamilton | I |
| Aberdeo | Dundee Utd | I |
| Falkirk | Kilmarnok | x2 |
| Hears | Clyde | I |
| Motherwell | St. Mirren | I |
| Rangers | Morron | Ix |
| St. J'atone | Partick | I |

## Scottish Div II

| | | |
|---|---|---|
| Albion R | Raith R | I |
| Allon | Queen's PK. | I |
| Ayr. Utd. | E. Stirling | I |

### 12 Homes

Leicester v Sheff W
L verpool v Arsenal
Sheff U v Notts 7
Bristol C v Middlesborough
Cardiff v Preton
Man City v Leyton O
Rotherham v Birmingham
Wolves v Ipswich
Hull C v Bristol R
Peterborough v Swansea
Reading v York
Matford v Southend

### 4 Aways

Blackool v Stoke
Sunderland v Man U
Coventry v Hudersfield
Bradford C x Newport

### 3 Draws

Tottenham v Chelsea
Westham v Newaastle
Coventry v Huddersfield
Norwich v Bolton
Exeter v Oxford
Q P R v Grimbsy
Barnsley v Torquay


## ALEBIOSU BOOKSHOP

13, BAMGBOSE STREET, PHONE (21304) LAGOS,

LADIES & GENTLEMEN/

As your problem is curs, therefore we have g t in St ck, Seasonal Lovely & interesting Xmas Cheques and Xmas Cards in assorted types as:-

1 To my Darling
2 To my Sweet He rt
3 ,, my Lover
4 ,, One I Love most
5 ,, my Boy Friend
6 ,, Husband
7 ,, my Wife
8 ,, my Sister
9 ,, Broth:r
10 ,, my Friend

You will be mostly impressed if you come to the above named Bookshop for your Seasonal Greeting Cheques & Xmas Cards.

WISHING YOU HAPPY CHRISTMAS IN ADVANCE




Aworan oke yi n ti nigbati awon osisę Imototo ile ise Domisile de ile obinrin Abiyamo na ti nwon fe wo inu rę ti obinrin na si wa pade won ni oja ona lenu ona ile rę Bi obinrin na ti se gbo ohun awon enia na lo ti yara tete dide ti o si ki won toyaya toyaya o si pe awon enia na wipe ki nwon wole wawo omo on ti nwon wa se itoju rę


## EGBOGI JEDIJEDI

BERE FUN EGBOGI

### "CYCLEVEN"

Arun Jędijędi ję okan ninu amodi ti o buru ni patak fun Okunrin ti o si lagbara lati şe iwosan rę patapata;

Opọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri odę nisisiyi ti wọn a ma polowo wọn fun iwosan rę şugbọn boya ki le ri męwa ninu ogorun ti o le şe iwosan arun yi daradara. Awọn ęlomiran lere wipeboya bi awọn ba lọ si ile Dokita lati lo ke eyiti o ba nyo jade lati omusu ku ni, pa bę awon o bo lowo rę palapata

Şugbọn awa ko ro bę rara: Lęnin odun nię iyonu rę yio sitnn ma bęrę bakanna, Orisirişi Jędijędi ni o wa ekini ti o bęrę nipa aiko ma şe igbonse dede tabi lojojumo, elomiran nipa ijoko ni ojukanna selu lojojumo tabi gigun keke ylogere (Basikulu) pupo elomiran ewe nipa jije Şuga tabi onirurn ohun adidun popo ju. Jedijedi orişirişi ni o wa ewo ni tirę? Bi o ba nyo jade ninu olusu ta i ti o ba nmu wa lęhin igbonsę tabi ba uyo ti o ba şe igbonsę tan ni, tabi ti nr n o ninu musu ni eyikeyi ti o bara bere egboki "CYCLOVEN" ti awon Oyinbo Jamani fere wa id rę ko ki o si dan wo o işi meta nio da u wipe iwo yio bo lowo Je i p tapata alafia yio de si eke,l re ko si ninu gbogbo egbogi sa igboro ilu Nsina Bere re ni:—

Waterloo Medecine Stores
8 Palm Church Streer Lagos

# IROHIN IMOLE

IMOLẸ ỌRẸ AIYE TẸNI GBOGBO LAWA

No 1,583 SATURDAY DECEMBER 11, 1965 (2D)


## Nwon Pa Ogun Enia Ni Oshun

OSHUN:— Ninu irohin kan to de ile iṣẹ wa ni owurọ ọjọ Iẹgun ti iṣe ọjọ keje oṣu yi ni irohin awọn Ọlọpa lati ilu Ibadan fi ye wa pe Ogun enia lo padanu ẹmi wọn ti ọkẹaimọye awọn enia ti fi ara gbọgbẹ ninu rogbodiyan kan to bẹ silẹ larin awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu lori abayọri idibo si ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria eyiti nwọn ṣe idibo re ni ọjọ kankanla oṣu kẹwa ọdun yi.

Irohin lati ọwọ awọn Ọlọpa ilu Ibadan fi ye wa pe lati ọsẹ to ti kọja lọ yi ni rogbodiyan ti nṣẹlẹ larin awọn ẹgbẹ oṣelu eyiti o jẹ wipe ọpọlọpọ awọn enia lo wa ninu ile iwosan lori iṣẹlẹ to ṣẹlẹ ni agbegbe Oshun.

Irohin tun fi ye wa pe awọn ọlọpa ti mu enia mẹtadinlogun lori iṣẹlẹ ti o nṣẹlẹ ni agbegbe Oshun eyiti o jẹ pe awọn enia [illegible]dinlogun ti nwọn mu [illegible] ti tiwọn mọle ni Te[illegible] Ọlọpa bayi.

Oniwe irohin wa to wa ni agbegbe Oshun fi ye wa pe nwọn ti ko awọn Ọlọpa lọ si awọn ibiti rogbodiyan na ti nbẹ silẹ bayi lati lọ ṣe eto bi rogbodiyan na yio ṣe lọ si opin.

# NWỌN FẸ ṢE IWADI ILE-IṢẸ ỌKỌ RELUWE

EKO:— Igbimọ ti nmojuto ọkọ Reluwe ṣe pinnu lati ṣe iwadi lori inakuna, aiṣodeede ati ọna ti nwọn fi nṣe awọn eru kan ni iṣekuṣe eyiti o mu adanu ati ofo ba ọkọ reluwe, nwon yio ṣe iwadi na larin arawọn atipe iwadi na yio jẹ ti ile ola ti nwọn npa ẹru mọ si.

Ẹniti yio ṣe alaga igbimọ iwadi na ni Oloye Alhaji I. S. A. Adewale ẹnit gbogbo enia mọ oruko re ni "Ọmọ na dera" ti o tun jẹ gbajumo agbẹjọro ni igboro ilu Eko ti o si tun jẹ ọkan ninu igbimọ ti o nmojuto ọkọ reluwe.

Gẹgẹbi ọrọ kan ti a nyọ gbọ lati ile iṣẹ ọkọ reluwe fi ye wa pe, iwadi ti Oloye Adewale fẹ ṣe yi ni yio di ẹkẹrin ti nwọn nṣe ni larin awọn orisirisi ile iṣẹ ti o wa nibi ṣe ọkọ reluwe lori inakuna ati aidọgba awọn nkan miran.

Irohin fi ye wa pe Iwadi yio tun wa ọna ti ibi iṣẹ ọkọ reluwe yio mori bọ ninu gbese aijẹtu iṣẹ Iwadi ile ola ti nwọn nko ẹru si yio sọ bi nwọn ti nsan owo ju iye ọna ti nwọn ra lọ papa ohunti nwọn nfi nlo lrin pọ Owo ti nwọn san le lori awọn nkan ti nwọn ra yi ti pọ kọja eyini o fa ti igbimọ na fi sọ pe gbogbo iṣẹ na wa lori iwa jibiti

Diẹ ninu awọn ọga ibiṣẹ na ni nwọn ti iwadi ọrọ lẹnu wọn bayi a ko ti mọ iye ti oro na jẹ bayi

Iwadi miran tun ti bẹrẹ larin awọn akọwe ti nmojuto awọn akọsilẹ iwe ẹniti yio ṣe alaga iwadi na ni Ọgbẹni J O B Ọmọtọsho agbẹjọro kan ti o wa ni Ibadan a si tun ti gbọ pe nwọn ti nwadi ọrọ lẹnu awon oga ibi ṣẹ na bayi irohin ta sọ pe awon ti nt in ẹrọ ọkọ reluwe ṣe nlo awọn ohun elo na fun arawọn

Minista ti nmojuto ọkọ Reluwe ati igbokegbodo Alhaji Zanna Bukar Dipcharima ti ṣe ileri pe on yio ri pe gbogbo aiṣedeede ati aidọgba ti o wa nibi iṣẹ ọkọ reluwe pari ki on to ṣe irin ajo si ilu okere



Alhaji Zana Bukar Dipcharima

# Okunrin Kan Pa Ara Rẹ

## Lati Oju Ewe Kini

Ninu ọrọ ti awọn enia ti o ngbe ninu ile ti okunrin na ngbe ni o tun ṣe alaye fun oniwe irohin wa pe lati nkan bi oṣu mẹta ni aisan ti kọlu ọkunrin na eyiti o fi jẹ wipe o si ti lọ ri awọn Dokita mẹta lori aisan to kọlu na.

Oniwe irohin wa tun fi ye wa ninu irohin rẹ pe awọn Ọlọpa ti lọ si ile okunrin na ati pe nwọn si ti gbe oku okunrin na lọ si ile iwoṣan ti awọn lakulaku ti ilu Kano lati lọ ṣe ayẹwo rẹ. Bakanna ni awọn Ọlọpa ti gba ibọn ti okunrin na fi pa ara rẹ lọ si Teṣan wọn pelu awọn ọta ti nwọn fi nyin ibọn na pelu ninu yara okunrin na.

Awọn Ọlọpa ti bẹrẹsi ṣe iwadi lori ohunti yio mu okunrin na yin ibọn pa ara rẹ ati pe ọpọlọpọ awọn enia ni awọn Ọlọpa ti mu lọ si Teṣan wọn lati ṣe iwadi lẹnu wọn lori iku ti okunrin na ku.


## ALEBIOSU BOOKSHOP

13, BAMGBOSE STREET, PHONE (21304) LAGOS.

LADIES & GENTLEMEN/

As your problem is ours, therefore we have got in Stock, Seasonal Lovely & interesting Xmas Cheques and Xmas Cards in assorted types as:-

| | |
|---|---|
| 1 To my Darling | 2 To my Sweet Heart |
| 3 ,, my Lover | 4 ,, One I Love most |
| 5 ,, my Boy Friend | 6 ,, Husband |
| 7 ,, my Wife | 8 ,, my Sister |
| 9 ,, Brother | 10 ,, my Friend |

You will be mostly impressed if you come to the above named Bookshop for your Seasonal Greeting Cheques & Xmas Cards.

WISHING YOU HAPPY CHRISTMAS IN ADVANCE



E Maa Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ Ki E Si Maa Polowo Ọja Nyin Sinu Rẹ



Printed & Published by Mafuyọ Printing Press 16, Bamgbose Street, Lagos Phone 21985 Editor: TUNJI ADEBOYUN 45 Campbell Street Lagos. 11/12/65